Dajudaju Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- kọ fun yin lati maa bura pẹlu awọn baba yin

Lati ọdọ Umar ọmọ Al-Khattaab- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Dajudaju Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- kọ fun yin lati maa bura pẹlu awọn baba yin", Umar sọ pe: Mo fi Ọlọhun bura, mi ko bura pẹlu rẹ lati igba ti mo ti gbọ́ ti ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti kọ kuro nibẹ ni ti ẹni ti o mọọmọ tabi ni ẹni tí ó gbé ìbúra ẹlòmíràn pẹ̀lú rẹ wa.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe dajudaju Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- kọ kuro nibi bibura pẹlu awọn baba, ẹni ti o ba fẹ búra, ko gbọdọ bura afi pẹlu Ọlọhun, ko si gbọdọ bura pẹlu ẹni ti o yàtọ̀ si i. Lẹyin naa, Umar ọmọ Al-Khattaab- ki Ọlọhun yọnu si i- sọ pe oun ko bura pẹlu rẹ lati igba ti o ti gbọ́ ti ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti kọ kuro nibi ìyẹn, ni ẹni ti o mọọmọ tabi ni ẹni ti o n gbé ọrọ ẹni ti o yàtọ̀ si i wa ti o bura pẹlu ẹni ti o yàtọ̀ si Ọlọhun.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/2945

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee